# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

NO 863 FRIDAY DECEMBER 4, 1964 (2D


## Idibo Si Ile Igbimọ Apapọ Yio Waiye Losu Yi

EKO:— Gẹgẹbi irohin to ti njade ninu awọn iwe ironin lati igba yi lori eto idibo to mbọ yi ni irohin na tun fi ye wa labẹlẹ pe ibo didi yio waiye ninu oṣu ti a wa yi ati pe ohun ti yio jẹ ki o ri bẹ ni eto orukọ awọn Adibo ilẹ Naijiria ni irohin fi ye wa pe nwọn ti nko lọ si gbogbo awọn ipinlẹ Naijiria bayi.

Ṣugbọn a ko ti mọ boya gbogbo orukọ awọn enia ti yio dibo ni ilẹ Naijiria ni ti pari bayi. Ṣugbọn eleyi ti fi han pe idibo ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ni lati ṣiaiye ninu osu ti a wa bayi ṣugbọn a wo ti mọ ọjọ ti nwọn yio dibo na.

Ṣugbọn irohin na tun fi ye wa pe o se ise ki nwọn tu ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ka lẹṣẹkẹṣẹ ti Alakoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ba ti de si ilu Eko lati ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria. Alhaji Abubakar si wa ni ilu rẹ Bauchi ni ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria bayi.

## Ẹgbẹ UPGA Sọ Pe:

# ẸGBẸ NNA BA ADEHUN ẸTO ALAFIA IBO JẸ

**EKO:— Ni ọjọ Bọ ti iṣe ọjọ kẹta osu yi ni irohin de ọwọ wa lati ile iṣẹ eto irohin fun ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA eyi ti yio jẹ irohin ẹkini ti nwọn yio kọ gbe jade lori eto adehun ti awọn Olori ẹgbẹ Oselu se lori eto idibo to mbọ yi, ile iṣẹ eto irohin ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA na tun se alaye ninu irohin wọn pe ni ọjọ kẹtalelogun osu kẹwa ọdun yi ni awọn Olori ẹgbẹ Oselu ilẹ Naijiria se eto ofin lori adehun eto ipolowo idibo to mbọ yi.**

Irohin lati ile isẹ eto irohin ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria na se alaye pe ẹgbẹ Demọ (NNDP) ti nse akoso Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun ati Olomi (NPC) ti nse akoso Ijọba ipinlẹ Ariwa ile Naijiria ni awọn Olori ẹgbẹ mejeji na si fi ọwọ si adehun eto idibo to mbọ yi.

Ninu eto ofin adehun lori idibo to mbọ na ti awọn Olori ẹgbẹ oselu ni ilẹ Naijiria ti se awọn adehun wọnyi eyi to jẹ pe gbogbo awọn Olori ẹgbẹ oselu to pese ṣibi ipade ọjọ na ti nwọn si fi ọwọ si ofin na loruko ẹgbẹ wọn.

Awọn olori ẹgbẹ oṣelu na si ṣe ofin pe gbogbo ọlọpa ti Ijọba Ibilẹ to wa ni gbogbo Ipinlẹ Naijiria ni yio wa labẹ akoso awọn ọlọpa ti ilẹ Naijiria ti yio jẹ pe ọga agba awọn ọlọpa ilẹ Naijiria ni yio ma ṣe akoṣo gbogbo wọn lasiko ti nwọn yio fi se idibo si ile Igbimọ Asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijira.

Awọn olori ẹgbẹ oṣelu na tun ṣe ofin pe gbogbo awọn ẹgbẹ oṣelu ni lati ni anfani lati ṣe ipade ipolowo ibo ni jakejado ilẹ Naijiria laisi pe awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan nkọlu wọn tabi Ijọba Ibilẹ kan nsọ pe nwọn ko fun wọn laye lati ṣe ipade na. Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun ṣe adehun lori pe ibi to ba wu awọn ẹgbẹ oṣelu ilẹ Naijiria ni nwọn le rin de laisi pe enia kan tabi awọn enia kan ndi wọn lọwọ tabi pe ki nwọn ma fun wọn laye lati ṣe ipade ni ibikibi to ba wu wọn ni orilẹ ede Naijiria

Awọn olorięgbẹ oṣelu tun ṣe ofin pe Ijọba ni ati fun awọn ẹgbẹ oṣelu lati sọrọ sinu ẹrọ asọrọ magbesi ati pe ki Ijọba tun fun gbogbo ẹgbẹ oselu ni aye lati le tẹ ọrọ ti nwọn ba sọ sinu iwe irohin ti ba jẹ ti Ijọba.



DOKITA M .I OKPARA
Olori Ẹgbẹ Alakukọ

Ninu awọn eto ti awọn Olori ẹgbẹ Oṣelu ṣe ofin le ni pe ko gbọdọ si iyatọ lori pe ki nwọn fun awọn ẹgbẹ Oṣelu laye lati ṣe ipade ati pe ko gbọdọ si pe nwọn ṣe ofin pe ko gbọdọ si pe ki awọn enia ṣe ipade tabi ki nwọn ṣe ipade iwọde gbangba.

Awọn Olori ẹgbẹ Oṣelu na tun ṣe ofin pe awọn gbogbo ẹgbẹ oṣelu ni lati kilọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ wọn pe ko gbọdọ si iwa janduku tabi ki nwọn kọlu ọmọ ẹgbẹ oṣelu miran ati pe adehun ti nwọn ṣe na pe awọn ẹgbẹ Oṣelu ni lati jẹ ki irohin na lọ kakiri

Awọn ọmọ ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA ṣe alaye ninu Irohin to jade lati ile iṣẹ eto Irohn wọn pe ko pẹ ti nwọn ṣe ofin lori adehun na ti ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) ati ẹgbẹ Olo- (NPC) si bere lu ofin na ti nwọn ko kọ ibi ara si.

Irohin lati ile iṣẹ eto Irohin ẹgbe ilọsiwaju ile Naijiria UPGA ni nwọn ti fi ye wa lori gẹgẹbi nwọn ṣe lu ofin na.

Ni ọjọ kẹtalelogun oṣu kẹwa Ọdun yi awọn Olori ẹgbẹ Oṣelu na ko ti fi ibi ti nwọn ti lọ ṣe ipade silẹ ni igbati awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA sọ pe nwọn gbọ Irohin pe Ijọba ti ẹgbẹ Dẹmọ NNDP nṣe akoso rẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun ti gba aṣẹ agbara lati fun awọn ẹgbẹ Oṣelu ni aye lati ṣe ipade eyi ti o ti wa lọwọ awọn ọlọpa ilẹ Naijiria ti nwọn gba lọwọ wọn ti nwọn gbe si ọwọ ọlọpa ti Ijọba ibilẹ ipinlẹ Iwọ orun Naijiria eyi ti awọn ọmọ ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA sọ pe ọkan ninu awọn okuta gbogbo lori eto ofin ti awọn olori ẹgbẹ oṣelu na ṣe.

Irohin tun fi ye wa pe ni



Alhaji Ahmadu Bello
Olori Ẹgbẹ Olomi

ọjọ kẹtalelogun oṣu kẹwa kanna ni awọn ọlọpa ti Ijọba ibilẹ ipinlẹ Iwọ orun lọ si ile iṣẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ ti nwọn si bẹrẹ si ni tu awọn ile na eyi to jẹ pe awọn ọlọpa Ijọba ibilẹ na bẹrẹsi ni halẹ mọ awọn oṣiṣẹ ile iṣẹ ẹgbẹ mejeji na.

Ni ọjọ kerinlelogun oṣu kẹwa ọdun yi ni ẹgbe Dẹmọ NNDP ti nṣe akoso ile ẹkọ giga Unifasiti ti Ifẹ sọ fun Dọkita M .I Okpara lati ma wa si ile ẹkọ na lati wa fun awọn ọmọ ile ẹkọ na ni eto ẹkọ, eyi ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe alaye pe awọn Alakoso ile ẹkọ na ko fun awọn Akẹkọ na laye lati jade.

Ni ọjọ karundinlọgbọn oṣu kẹwa ọdun yi ni awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA sọ pe

WO OJU EWE KẸFA


**UPGA Flag Now Ready**

FLY UPGA FLAG FOR UNITY, PROGRESS, PROSPERITY & STABILITY
OBTAINABLE AT UPGA BUREAU OF PUBLICITY & INFORMATION
2 NNMADI AZIKIWE STREET, LAGOS
PHONE: 24381 & 22637
PRICES: CAR SIZE 6/- LARGE SIZE 35/
LIMITED QUANTITY AVAILABLE

# Kini Ero Ọkan Rẹ Lori Ibo To Mbọ Yi ?

### Lati Ọwo Ibaka

Ẹnyin enia mi lọkunrin ati lobinrin paapa julọ ẹyin to nka iwe Irohin Imọlẹ lojojumọ mo tọrọ aforiji lori ọrọ mi ti ẹ ko ri ka ninu iwe yi lati nkan bi ọsẹ meji s'ẹhin ohun to fa eleyi wa ni akitiyan ti mo nṣe lori gẹgẹbi awọn ẹgbẹ Oṣelu ilẹ Naijiria ti nṣe ipolowo ibo wọn, awọn akiyesi ti mo nṣe nipa rẹ ni ọrọ ti awọn ẹgbẹ Oṣelu wa ma nsọ eyi ti mo nṣe akiyesi lati mọ otitọ ati irọ ti olukuluku wọn ma nsọ fun awọn Olugbe Ilẹ Naijiria.



DOKITA M. I. OKPARA

Ẹnyin enia mi ni ilẹ Naijiria paapa julọ ni ilẹ Yoruba ati ni ilẹ Igbomina mo si fẹ bẹrẹ ero ọkan Olukuluku nyin lori eto ibo to mbọ yi. Gẹgẹbi ọrọ ti mo ma ngbọ lẹnu awọn ẹgbẹ Oṣelu kan ti a ma npe ni UPGA eyi ti nwọn sọ pe ibo ọdun yi jẹ "Ajalọ Orungbe" Ṣugbọn nigbati mo gbe Oye ọkan mi wo nkan ti ọrọ ti nwọn ma nsọ na yio jasi ko tete ye mi ṣugbọn ni ikẹhin o ye mi lati oke de ilẹ pe otitọ patapata gan an ni ọrọ na jẹ

Ẹnyin ọmọ ilẹ Yoruba ati ọmọ ilẹ Igbomina otitọ ọrọ ni awọn ẹgbẹ oṣelu na nsọ lori pe idibo ti ọdun yi jẹ "Ajalọ Orungbe" eyi ni nwọn pe ni ede Gẹẹsi ni "Operation Totality" Mo si fẹ ki Olukaluku nyin lọ mọ pe ibo ti a o di ninu ọdun yi ki iṣe fun ti ara ẹni bi ko ṣe pe fun awọn ọmọ wa to wa lẹhin ati awọn eyi ti nwọn ko ti si ni aiye otitọ ni a o ṣe idibo miran ṣugbọn eleyi yio jẹ ttan fun nwọn ọmọ nyin ti yio jẹ iran ẹkẹwa

Nitori eyi ẹ ma ṣe ro pe lori ki ẹ le ri owo gba lọwọ ẹgbẹ oṣelu ti a ti mọ tẹlẹ pe iwa wọn ko dara eyi to jẹ pe ọdalẹ ni awọn ẹgbẹ oṣelu iru eyi jẹ ni ilẹ Yoruba ati pe ẹnyin ọmọ ilẹ Igbomina mo ro pe ti ẹ ba gbe oye inu nyin wo iru ipo ti ilẹ nyin wa ninu ilẹ Naijiria ẹ o si mọ pe ko si ilọsiwaju kankan ti ilu nyin ni ṣugbọn awọn akọ enia to le ṣe

bi ilọsiwaju le ṣe wa fun nyin mo ro pe on lo jẹ ọta awọn enia kan ti oju inu wọn ti fọ lọjọ to ti pẹ

Nitori eyi o di ọwọ nyin o si di ọwọ Ọlọrun Ẹnyin ọmọ ilẹ ipinlẹ Iwọ Orun ẹmi ko gbọdọ ri ki ma sọ fun nyin eyi ti iru nyin ni ki ẹ ṣe to ba owu nyin ki ẹ titori owo ni ki ẹ gbe nkan ti yio ṣe ọmọ nyin ni nla to titun nyin njuja ẹlọ ro eyi dada ki ẹ dibo nyin fun ẹgbẹ ti yio fa anfani, alafia ati ilọsiwaju ba ẹnyin ati ọmọ nyin.

Mo fẹ ki ẹ lẹ mọ daju pe ni ọjọ ti ẹ so dibọ nyin ki ẹ lọ ro ọrọ mi yi jinlẹ ki ẹ to ju ibo nyin si apoti ibo ẹgbẹ oṣelu ti yio mu ilọsiwaju ba nyin,



OLOYE AWOLỌWỌ

anfani lẹhin ọla ki ẹ gbe ta ṣugbọn ẹnyin ni yio sọkun rẹ lẹhin ọla eyi to jẹ pe nkan ti ọmọ nyin iran ẹkẹwa yio fi wa ṣe epe si nyin.

Nitori na ẹ lo sun ki a ronu nyin jinlẹ ki ẹ dibo nyin fun ẹgbẹ ti yio fẹ nkan rere wa si ilu nyin lẹhin ọla ati paapa ki ẹ ma ṣe gbagbe olore

Ọrọ mi ko ni pọ pupọ ju nitori mo ngbiyanju lati fi ọrọ na wa awọn ẹgbẹ Oṣelu lẹnu wo karikari hoya to ba ṣe iṣẹ ma gbinyanju lati ri irin esẹ mi si ọdọ awọn ọmọ ilẹ Igbomina lati fi ọrọ jomitoro ọrọ lẹnu wọn ki nsi mọ iru aye ti awọn enia ilẹ Igbomina wa mo si kan saa a si awọn enia kan bayi ninu awọn ọmọ ilẹ Igbomina awọn enia na ni Ọgbẹni J. K. Balogun, Timothy Akanbi ati Ogbeni Ṣanusi ati awọn ti mi ko ranti orukọ wọn mọ ṣugbọn mo kan yin wọn diẹ o di akoko ti nwọn ba ṣe iṣẹ wọn de ibi ti yio jẹ pe yio si yọri si rere ki nto mo pe ọmọ ọkọ ni wọn iṣe .

Ẹnyin enia mi ni ọjọ idibo ti ẹ ba ju ibo nyin sinu apoti ibo ti ẹ ba ti ju si apoti ẹgbẹ ti yio ṣe ọmọ nyin ni rere ati pe mo fẹ ki ẹ gbagbọ pe ki ẹ ma ṣe ju ibo nyin sinu apoti ibo na ni ki ẹ ṣe iranti pe bi igbesi aiye nyin ati awọn ọmọ nyin yio ṣe dara ni ẹ o ṣe ju si apoti ẹgbẹ Oṣelu ti yio ṣe ore fun nyin lasiko ibo ṣugbọn ẹnyin to jẹ pe lori owo ni ẹ fi lọ dibo ni ọjọ



OLOYE AKINTỌLA

na ẹ o ṣi mọ pe Igbesi aiye nyin ati ti ọmọ nyin ni ẹ ta fun ẹgbẹ oṣelu ti ẹ ju ibo nyin si apoti rẹ nitori eyi o di ọmọ nyin o di ọwọ Ọlọrun.

Ẹnyin ọmọ ilẹ Igbomina ẹ ma ṣe jaya ki ẹ ro nkan ti oju nyin ti ri ki ẹ lọ si ilu nyin lati lọ dibo fun ọmọ nyin ẹni ti o mọ iyi nyin yatọ si ẹgbẹ oṣelu ti ko mọ pe ẹ wa laiye. Ṣugbọn ti ẹ ko ba ro iru wahala ti oju nyin ti ri ki ẹ tete yi ọkan nyin pada ki ẹ tete lọ si ilu nyin ki lọ dibo fun ẹni rere awọn enia ti yio le ja fun nyin ti nwọn ba de ile Igbimọ aṣofin lẹhin ibo yi. Odigba diẹ a o si ba ara wa pade pẹlu ayọ Amin.

---

## ẸDA TO MO ỌLA KOSI

### LATI ỌWỌ ABIỌLA BOLARINWA

O Bẹrẹ Lati Ana

Ṣugbọn ngo fẹ ti o ba lọ lo ipin rẹ gẹgẹbi aiye rẹ lati ẹhin wa tirẹ ni Ijiṣe..

Nitori ngo fẹ ni o wa ẹniti yio ma ṣe itoju aja ra rẹ fun ọ ma ṣe fo ya o fi odindi Malu mẹrin ta lọrẹ fun aṣe oku baba rẹ o si tun fun un ni owo to to owo ṣugbon gẹgẹbi o fi nfun ni awọn wọnyi ni nwọn bayi pe.

Gẹgẹbi Iwa rẹ Iwa rere lẹṣọ enia. Ni o ba fun ni Kẹkẹ olongere kan lati mu lọ ati lati le fi ko ẹru pẹlu awọn ohun ini rẹ si Igbati awọn yoku re ri ohun ribiribi ti ọga fi ta ekeji nwọn lọrẹ nṣe ni, nwọn tun bẹrẹ si ni huwa rere wọn ko lai ṣe ojutu Ṣugbọn ohun ti Oloye wọn ni lọle rẹ gegẹbi ileri fun Onikaluku wọn, nwọn mọ bẹni nwọn ko sun ki wọn. Ṣe si laala ri tabi ki nwọn jọ ebọ. Ṣugbọn eleyi han si Oluwa Elod mare pẹlu ọga won. Bi ẹni bi

WO OJU EWE KARUN

# IWE SI OLOTU

## Mo Kan Saara Si Adegbenro

Olotu jowo gba mi ni aye die ninu iwe nyin to kan fun ogbọn ati oye lati ki Adele olori ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ Alhaji Daudu Soroye Adegbenro ori iṣẹ ti o nṣe gẹgẹbi Asiwaju fun nwọn ẹ ọ ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Mo si rọ Alhaji D. S. Adegbenro ki o ma se foga rara ati pe idaniloju si ti wa pe lagbara Oluwa on yio di Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun eyi ti ẹgbẹ Afẹnifere yio sẹ akoko rẹ lehin idibo si ilẹ igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Nairia to mbọ yi.



Alhaji D. S. Adegbenro

Awa ọmọ Ogbomọshọ si wa hun ẹgbẹ Afẹnifere nigba gbogbo ti iṣẹ ẹgbẹ ti Baba Layinka nṣe ori re joko to wa ni du Ogbomo ninu ibo to mbọ yi ti ẹgbẹ Afẹnifere ni iṣe olotu mo dupẹ fun ye ti ẹ gba mi.

Emi ni
Sunday Ogunbọ[illegible]
OGBOMỌSHỌ.

pẹ O.

Emi ni
P.O Oshinukan
EKO

## Ẹgba Ko Si Lẹhin Ẹgbẹ Dẹmo

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin Oloyinmọmọ lati fi ye awọn olori ẹgbẹ Dẹmọnu NNDP to wa ni Ilu Abẹokuta pe awa ko fi igba kan kuro lẹhin ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ nitori na ẹnikẹni ninu awọn ọmọ ẹgbẹ NNDP to ba gbe apoti ibo silẹ ni ilu Abẹokuta ati agbegbe rẹ yio padanu owo isan tẹlẹ owo ibo re ati papa fun awọn kan to fi ẹgbẹ Dọmọnu njẹun ki nwọn tete pada si ẹgbẹ Alakukọ ati Afẹnifẹre eyi ti iṣe ẹgbẹ Ọmọluwabi,

## Ẹku iṣẹ o Masha

Olotu inu mi yio dun bi e ba le gba mi ni aye ninu iwe nyin oloyinmọmọ ati kesi Alaga ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ ilu Eko Alhaji A. F. Masha ati awọn ọmọ ile Igbimọ na paapa julọ awọn to wa ninu Igbimọ ti nṣe itọju ilu.

Eleyi fi han pe awọn ọmọ ile Igbimọ ti Ijọba Ibilẹ na si mu ileri ti wọn lasiko idibo ṣe pe ti wọn ba ti wole ibo si ile Igbimọ ti Ijọba Ibilẹ na awọn yio si gbiyanju nwọn yio se tun awọn ona ati Gọta to wa larin ilu Eko ati agbegbe rẹ ṣe eyi si fi han pe ko si ohun kan ti ẹgbẹ Afẹnifẹre le tabi ọmọ wọn le ki nkan ma ṣe nitori eyi mo n rọ awọn enia ilu Eko ki wọn ti dibo fun ẹgbẹ Alakukọ ati Afẹnifẹre ninu idibo to mbọ yi. Olotu mo dupẹ du-



Oloye S. L. Akintọla

Eleyi ni lati fi han si oju olori egbe Dẹmọ ni Abeokuta pe awa ko fi igba kan kuro lẹhin ẹgbe Afẹnifere rara. Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
Adewale Karimu
ABEOKUTA


## Kini E Nduro Fun ?

Bi o ba ni asọ fun fifọ ati lilọ bi ( wollen ), asọ oke, Tapẹta Sapeti ati orişirişi asọ ti o ba ni fun fifọ ati lilọ ni iṣẹju kan

TETE GBE WA SI ỌDỌ
**JOYCE LAUNDRETTE SERVICE**
**34, Ojo — Oniyun Street,**
**Apapa Road Ebute Mẹta.**

Kia ni ao ba ọ fọ ti o si ri gba ni ẹsẹ kanna. A le wa gba ni ile rẹ, ki a si ko pada fun ọ ti a ba fọ tan kọ nomba ile rẹ ranṣẹ si wa.
Dan wa wo lẹkansoso ki o si ri bi iṣẹ wa ti dara tu
Owo pọọku ni a si ngba.

## Aiye Toto African Healng Home

Bere ogun itaja Ti o daju Ti a şe ni Turari pẹlu lọfinda. Tete ra tirẹ ki o gbadun rẹ Irohin ko te Afojuba orişirişi aruu ati ilọsiwaju
Lẹnu işẹpẹlu Ajẹbina ogun awọn Agba lo wa lọdọ w

Office
7. Tadeyọ Road
Mushin

S. ỌLATUNDE
Native Doctor
6, Tadeyọ Rd
Mushin

## EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBOGI

Aworan ẹgbọ yi fihan gban gba ibiti Jẹdijẹdi rẹ wa ni ara rẹ ti ayọọ iṣan nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi iho idi enia ibiti a ma ngba şe igbọnşẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun ọkunrin ti o si soro pupọ lati şe iwosan rẹ patapata.



CYCLOVEN

Ọpolopọ egbogi ni o wa ti a nta kakiri ode nisisiyi ti nwọn ma a npolowo nwọn fun iwosan rẹ şugbọn boya ni a le ri mewa ninu awọn ogun ti o lese iwosan arun na daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn gbe lọ si ile iwosan lati lọ ge eyiti o ba nyọ jade omusu ku nipa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patpaata.

Şugbọn awa ko ro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun berẹ bakana Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa Ekini ti o berẹ nipa aiko ma şe igbọsẹ dede tabi lojojumọ ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pupọ ojojumọ abi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwu eran Şuga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba Jedijẹdi orisirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ sode ninu or uşu tebi ti o ba nmu ejẹ walẹhin igbọnse tabi ti o ba nyọ ti o ba şe igbọnşẹ tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuşu ni eyikeyi ti o ba jẹ bere egbogi CYCLOVEN ati awọn Oyinbo Jamani şẹşẹ wa idi rẹ kio si danwọ kuaju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de ba ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo awọn ti a tanlgboro Naijiria bere ni :

NIGERIA MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos

# Imoran Nipa Ife Larin Okunrin Ati Obinrin

Lati Owo BOSEDE SHOYINKA

Mo ti fe Obinrin AREWA kan nigbati o han si mi pe o nto si ile, nko ko sile, mo gbiyanju titi lodo Babalawo gbogbo ogun ti nwon nse fun wa, ko si eyi ti o ba mu u



Nse ni iyawo mi na wa nto si ile gburu-gudu tisi-siyi sibesibe okan mi ko ko o, sugbon ohun ti o wa deru ba mi ni pe, nwon so wipe ti ito ti on ati ti omo ba papo lori eni, omo na yio ku, — Bosede Ogbagba ti gba ra adugbo, jowo fun mi ni imoran kikun

Emi ni Ogbeni A O
SHOMOLU VILLAGE
IMORAN

Imoran ti mo fe fun o yi le yato epe ti awon onkawe Irohin mi sugbon imoran temialara ni yen ohun ti mo gba o ni yanju pe ki o se ni pe ki o mu lo sodo Dokita Oyinbo fun itoju tabi odo Babalawo, ti ko ba si wa san ko o sile n'toripe aran buburu ni pe ki Obinrin abile ko ma to si ile.

Itan re ju ri eniti o jale lo, Nipa ti pe iro ni omo nko mo nipa iyen o

Emi ni Bosede
c/0 postal Agent
Iture.

# YE RAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Ma a gberadia fun ato ubo kan ti ebi tabi ore re kan yio se si o yio si gbidanwo lati ba alamori re je

PISCES (Feb 21 – Mar 20) Sora ki o ma ba ri oran isorikodo tabi ibanuju loni, ki ile to su nitoripe oro isorikodo ara han si o

ARIES (Mar 21 – April 20 Ojo oni dara ko ni si oro ohun gidi gidi tabi erepa kan ninu re gbogbo ohun ti o ba loro ti o fe se so di ola

TAURUS (April 21 - May 20) Ohun apejuwe fun fe ni Obinrin kan yio fi ia o lore loni, mase lo si ode to ina ojo oni yio jolo fun o ire mbe fun o.

GEMINI (May 21 – June 21) Awon eniti ko ni iyawo nile yio ri iyawo ojiji fe iru iyawo gbigbe bayi yio po larin awon ti o ba ti le ni odun medogun

CANCER (Ju e 22 - July 22 Obinrin kan ti ti nwa o, lati la lopo ni owo re yio te loni yala o wu o se tabi ko wu o iwo ni 1 ti se e ni.

LEO (July 23 - Aug 23) Bi iwo ko ba je faaji loni nse li o se ara re tan, faaji na yio si yori si rere, Are ko mu o, nse ni ara re yio ma le ti ugogo mejila oru yio fi 'oju.

VIRO (Aug 24 - Sept 23) Sora ki oma bi ke abamo loni.

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Je olotito ati Olododo bo fe bi awon ti o mba o lo papo ko mo iyi re mase fi evni se

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Ara yio ma fu gbogbo enia si o loni owo eni li a bi ntun iwa eni se oku si owo re bi iwo yio ti se oni ayo

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Onakona ni ayo yio fi kan o yara o fe tabi o ko chun kan ti o ti se eto re sile yio fre ati anfani wa fun o

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 21) Egbogi kan ti o ti se sile, yio mo anfani repete wa fun o loni, lati edo enikan ti o ti ngbaro ibi s io.

BI ARA RE SILE PATAPATA LOWO IKO BUBURU GBOGPO NIPA LILO EGBOGI:—

## RICHALET

dajitiro. Ise re lara k Kau fun Iwosan gbogo kokoro buburu t o bi FUN ARUN EJE ninu, EJE ARA bi Monamo-VRA EIA GBOGBO

Meji re ko si ni gbogbo awon Egbogi ti nwon npe ni TONIKI Eje ti nwon si nta Kakiri ni owo pooku adi owo tabi ki o lo nile ko di owo Iyen se ewo, a wa ki ta awon egbo i ba won yen rara tabi ti nwon npo ta ni ile yi.

Gegebi awon Onbiara wa ti mo irufe awon egbogi ba mon yen a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a rense fun tita lati awon il u Jamani Faranse ati awon Tatambulu si Itali je.

Mo daju pe, bi eje arb ko ba mo daradara awon amodiagbe ailera wonyi le se o L-kulaku orisirisi Inaru, Oju susu tabi didun, Jedijedi Ako ibu arun Edoki, Aya didun pupo ati Eku-r laya.

Ara riro lapalapa, Egbo-ese modi Apo ile to, e in didun tabi ibaradi riro pelu Egbogi RISALETI a ma a gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu eje re patapata yio si fo eje mo to nitoni pelu

Sa dan Igo re kan wo iwo yi si ma a rohin re fun elomiran pelu. PRICE 13/6d postage 36/




WATERLOO MEDICINE STORES
Palm church Street, Lagos

## Congreves Female Remedy

(FUN OBINRIN

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awon Obinrin ti o ba ni iyonu tabi amodi inu rirun nigbakugba ta i ni eko okan ehin didun ibadi wiwo tabi sisan ejedun ati tabi aikoto eje ara Inu gbigbona nigbakugbo Igba-aiye riro omu riro didun are atinu wa ni o ma nfa oyi-oju Ilaogun ara ese ara sisan eforí tabi pelu iba ati otutu Egbogi yi dara pupo julo fun itoju gbogbo Obinrin gegebi Ajo fun ilera ati orisirisi amodi miran ti o ma ayo won lenu ni iru nigbakugba pelu

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI AJO WON NPENI:-

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba laila k awon Orisirisi robirobi egbogi ti won ko wa nisisiyi to da awon agbalagba aiye atijo mn ati wipe ko si ohun ti ale fi iwe egbogi yi bi otutu iko iba, orere lukuluku onizbameji ti aiperi n yo enia lenu yala Omode tabi agbalagba ni yio se iwosan re bi danga ni bi oba ti ta die sinu omi ti o lowoyo ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun iton eti riro tabi se iwosan iyonu apo-ile-ito egbogi oju didun tabi ni ona-ofun didun, ati orisirisi omiran pelu won mbe ni 'ubu awon:-

NIGERIA – MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone :- 22878 Nigeria, (Oja
ATI NI SOBU
ISE-OLODUMARE DISPENSARY OKE BOLA
IBADAN.

# Irinajo Mi Si Agbo-Ile Ifẹlodun Apa 3

## Lati Owọ Ajẹgborodagba

Gẹgẹbi ibiti mo ba irohin irinajo mi si agbo ile Ifẹlodun de ni ijẹta ni ọnọ[tij alaga sọ nipa Oloye Phillip Afọlayan Gbenle.

O ṣe alaye nipa iwa re-re ti Oloye Gbenle nhu si tomọde tagba lọkunrin ati lobinrin, o si ṣe afikun ninu ọrọ rẹ pe iwa rere pelu oyaya ti Alaga Phillip Gbenle nhu ati inawo ti o tọ ni o gbe de aye ti o de yi, iwa rere na ni o mu awọn ẹbi rẹ fi oye yi da lọla, o ni nitori pe Alaga wa na ki fi ọ r ọ ẹnikẹni ti o ba ti jẹ ẹbi rẹ tabi ọmọ ilu rẹ paapa ọmọ ilẹ Igbomina ṣere lati yara ba ṣe iranlọwọ ti o ba gbe wa siwaju rẹ. O si tun dupẹ pupo lọwọ awọn ẹ b i Gbenle fun ọgbọn ati lakaye ti nwọn fi Phillip ṣe olori ẹbi wọn A le Oloye Gbenle ko inawo rẹ, O si ṣe adura fun Oloye na pe, ajẹ gbo, ajẹ tọ, Ade a pẹ lori Bata a pẹ leṣe, Oye a mọri O.

Lẹhin eyi ni o wa pe ọgbẹni Victor Ọna Ọlapọ, ti ile Eko gigajulọ Unifasi lati wa kawe ẹri ti gbogbo ẹbi Oloye Gbenle fi ọwọ si pe awọn fi Oloye Phillip jẹ oye olori Ẹbi Obenle ti Ijomu. Lẹhin ti o ka fun gbogbe enia tan ni o wa fi le Oloye na lọwọ.

Nigbati a fi iwe ẹri na le Oloye lọwọ ni iyaafin Lydi Okunloye Gbenle wa fi awọn nkan oye ti awọn ẹbi ra fun oloye na, awọn ni aṣọ Sanya olowo iyebiye, ilẹkẹ iyun ti owo ati ti orunpẹlu fila oye.

Ọgbẹni Ologbo Ọ l ọ j a Am delogun ni ilu Oai ti ṣe A, K. Folaji ti i l e Ifẹ bẹrẹ si lo ewọn nkan na fun Oloye Gbenle pẹlu adura atokan wa, bi Oloye paapa si ti gunwa ninu Ọla nla rẹ, ti o wa nrẹriu musẹn. O wọ ewu Sanyan nla fun Oloye na, lẹhin eyi o fi ilẹkẹ si lọru pẹlu ọwọ.

Nigbati a wọ gbogbo nkan wonyi ti ebi Oloye Gbenle fi da lọla tan, ni alaga wa sọ fun Oloye na pe bi ya on na le ni ọrọ ni iwọn ba ṣoki lati sọ lori ayẹyẹ ọjọ na.

Oloye na si dide lati sọ, rọ, bi Oloye ti fẹ ma sọrọ ni gbogbo awọn enia ba bẹrẹsi pelu ọgọ Oluwa loye on yio sa gbogbo nkan lọ



Oloye Phillip Ajiboye Gbenle

deede ni idile ẹbi Gbenle pe ilọsiwaju si wa ni ilẹ I g b o m i n a. o s i silo ati Oro, Ijomu ati jakejado le Igbomina ti o wa sibi iwuye na ba bẹrẹsi fi ẹsẹ ra ijo pẹlu Oloye na, ti gbogbo rẹ si ndun yungba.

O si fun gbeolurẹ fun gbogb ọmọ ilẹ Igbomina jakejado ilẹ Naijiria lẹhin eyi ni o wa tun dupẹ lọwọ gbogbo awọn alabaṣẹjẹ ọjọ na ti nwọn ti ọna jinjin wa o si gbadura fun won pe a de ile ba ire. arina ko rẹ Oluwa yio wa fi iṣọ rẹ sọ won.

Bi Oloyẹ ti npari ikini iṣẹ yin tan ni awọn onilu ba fi gongo wọn sọ ojo ilu ni ojo na, ni ijo ba berẹ ti Oloye ati awọn saraki saraki Olowo Oloro ilu

Gbogbo ilu si gbojikan fun ariwo ṣẹkẹrẹ ati aro ni ọjọ na ti o fi je pe niṣe ni gbogbo rẹ ndun yungba.

A fi ẹniti yio ba kegan Ajanaku ni yio sọ pe on ri kini kan fi ri ninu igba, ti a ba re esin ka sọ pe a ri esin, ko kuro ki tẹ nkan, fi eniti yio fẹ gbese awọn ebi ati Oloye Gbenle na wabiwọsi owo ni ojo na.

## Lati Oju Ewe Keji

eji ọlọjọ nde bọ si ọga Olori Iwọfa yi o pe awọn ẹni rẹ jọ o si wi fun bafun pe "Ọjọ kan nbọ ti Akukọ yio ko ifẹhin Ọkunrin" Ibẹni kan baba Beni kan Ọlọgbọn bẹ gẹgẹ ni ukan arẹṣa Igbakigba o ba wa ọ si ki Oluwa ma ṣe dojn ti ọ.

Tọju ile tọju Ọna ki o si tọju awọn Iwọfa rẹ Agbe arele re bo dọla Ni awọn yoku Iwọfa bẹrẹ si ni sọkun kikoro O wa bi ọkan ninu awọn Iwọfa yi pe anu rẹ ṣe? ti ẹnyin fi nsọkun kikoro. Iwọfa kan tun dide o wi bayi lohun aro pe. Awa nrira wa awa nyọ ṣẹṣẹ awa ngbọwọ jọ jin gin.

Igba kan li eyi ti awa nri ọ, ṣugbọn igba kan nbọ ti ao fẹ aworan tasi ojiji rẹ lati ri lai ko jẹ pe o tilẹ sọrọ rẹ siwa ṣugbọn he laipẹ jọjọ awa o ṣe afẹri rẹ. Ori olowo yi wu o si bu puru sẹkun ki orirẹ ran gbogbo wa o ami igbati oga yi sai kọ mi lati ọrun wa, ko pẹ, bẹ ni n ba pe awọn enia tirẹ pe awọn ẹbi Iwofa jẹ fun ọrọ ikẹhin ohun ti o sọ ni wipe gbogbo ohun ini on ki apakan ninu rẹ jẹ ti awọn Iwọfa ki apa keji rẹ ti awọn Ẹbi onun. Lotọ awọn ẹbi baba yi gba si baba wọn lẹnu nwọn ṣi ṣe gẹgẹbi o ti wi fun wọn. Ero awọn Iwọfa yi tẹlẹ ni pe bi awọn ti ṣe wa lọwọ o fo lati ile dee wọn ni awọn yio pada si.

Nito ina eyi ti baba ti le fi ọwọ ara re ṣ. fun a s a n ninu awọn ui- awọn t i l ẹ gbagbọ. Ṣugbọn lai ro tẹlẹ gẹgẹbi aṣa awọn baba n l a wa pe awọn ki i ,y. Ọ r ọ ana dapa bakanna ni ọ r ọ wọn otitọ ṣini. ki idaniloju ba le wa pin ogun yi ni Iṣoju baba wọn Pin Iwọfa yi bẹrẹ si ni iyo ko ju ọjọ kẹta lọ ni baba yi ba ti tẹru nipa. Ọna yi ni awọn Iwọfa yi bẹrẹ si bi mọ lemọ, loni kon ibẹ ni awọn g b a di Olowo, Ti nwọn ba si iwa hu ui asiko iṣẹ w ọ n ere yi ko ni jẹ ti wọn Ọna lo ji ẹru ni baba.

## Bọ Lọwọ Oso Ati Aje

Iwe egbogi Ajẹbidan 25/- mejila £2
Iwe Ilana Ifa Iyanrin titẹ ati etutu ṣiṣe pẹlu Iwe ṣan 20/- mejila £2 5/
Iwe Egbogi Awogba Arun 22/- meji 40-
Turari iṣẹgun Ajẹ, Oṣo ati awọn aba tẹnijẹ O wa fun itaja pẹlu alakala Pangolo 10/6- pakẹti 2/
Ki ṣe ti ẹnu fifọn bi o ra ninu awọn ọja yi aabo ti o nipon ni ile aiye ni yio wa lori rẹ ati awọn ẹbi rẹ
Fi owo ranṣẹ si

J.O. ,HOYINKA
11 Alaba Street
Oduabọrẹ Mushin.

